LAKAYE ORO

OJU Oluwa mbe lara awon olododo eti Re si si si igbe won.

Oju Oluwa kan si awon ti nṣe buburu lati ke iranti won kuro lori ile.

Awon olododo nke Oluwa si gbo, o si yo won lade kuro ninu ise won gbogbo.


# Irohin Yoruba

NO. 774 APRIL 6 — APRIL 12, 1960 Kobo Meji (2D.)


OWE

A NJUWON ko ṣe wi lejo tia ilara ko tan boro

Agbalagba ti yio te ile tutu yio da omi siwaju Igba ki i to lo bi orere aiye ki i to lo bi opa ibon.

# AWO YA! AṢỌ BO MỌ EGUNGUN LORI

ABULE IGBIRA

NI nkan bi agogo marun ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbon oṣu ti o kọja yi ni awọn egungun opidan mẹrin kan lọ ṣere ni adugbo ita Aorẹmukun leti abule Igbirra.

Ọpọlọpọ enia lo pejọ ni ibi ere yi lati woran bi awọn eegun wọnyi yio ti ṣe ma a yi aṣọ. Awọn egungun yi ṣe afojudi nitoripe ko juba awọn ọjẹ ti o wa ladugbo na ki nwọn to bẹrẹsi pidan.

Nwọn pe wọn, nwọn si kilọ fun wọn pe nwọn ko gbọdọ ṣere lai gba aṣẹ lẹnu awọn agba-ọjẹ adugbo, nwọn kosi bikita fun ikilọ yi nwọn si bẹrẹsi ṣele lọ. 'gbati ere wọ wọn lara tan, nwọn bẹrẹsi yi aṣọ. Bi olri won ti nwọn nje ni 'Pẹrẹblewebọ' ti o kọkọ bọ si agbo ti o si yi aṣọ tirẹ, larin gbogbo awọn ti o wa woran ni aṣọ ba bọ mọ lori ni o ba ara rẹ konbo ni ihoho ọmọluwabi kolombo ariwo wa bẹrẹsi ta gee, t'ọkunrin t'obirin ni o bẹrẹsi bo le e lori pe o bawoje; o bawoje! ole! olẹ. Itiju ọjọ na ko ṣe fẹnu so ni, awọn ọjẹ kanna ti o ba wọn soro ti nwọn ko gbọ, ni o ṣeṣe wa fẹhin pọn wọn lọ si

## Awọn ara Papalanto ṣe iranti eni ti o tẹ ilu wọn do

NIGBATI ọjọ ajọyọ na ti ku ọjọ marun ni awọn enia ti nwọn wa lati Abẹokuta ati awọn arọko ti o yi Papalanto ka, lati wa ba Bale ati awọn ọmọ Papalanto ṣe ajọyọ iranti Alaito ẹniti o tẹ Papalanto do ni odun jojo sẹhin. Gẹgẹbi awọn Opitan ti so ọ, nwọn ni ode ati agbẹ ni Alaito ṣe, ọmọ Owu ni Abẹokuta ni si i ṣe pelu. On ati iyawo rẹ Adeitan ni o si jijọ tẹ Papa do idi rẹ ti nwọn si fi npe ilu yi ni Papalanto niyẹn.

Ni owuro kutu-hai ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹdogbon oṣu ti o kọja yi ni ilu ti bẹrẹsi dun, awọn oloye at Balẹ Papa paapa ti ṣ'eṣọ, gbogbo ilu si pejọ si ita Balẹ, awọn iya agbaagba opitan paapa si wa nibẹ pelu.

Bale sọ orisirisi ọrọ pupọ nipa bi awọn babanla on ti ṣe tẹ Papa na do, ati iṣẹ ribiribi ti awọn Balẹ iṣaju on ti ṣe fun ilosiwaju ilu yi, o si tun dupẹ pupọ lọwọ awọn ilu fun inukan ti nwon fi nba on lo ti ko fi si ede-aiyede larin ilu

Gbogbo awọn Ijoye lọkunrin ati lobirin ni o soro aponle nipa Balẹ yi ati eniti o tẹ ilu na do. Lehin na ni nwọn wa pa ẹgboro malu kan, nwon fi se etutu pe ki agan ti ko romọ bi le fowọ s'osun pa omo lara ninu odun yi atipe ki Olorun le ba wọn le aisa buburu kuro larin ilu na. Gbogbo wọn si je ase anele ajọyọ na pelu ifẹ ni ajẹyọ.

Ni ọjọ keji ti aṣeyẹ na bere ti iṣe ọjọ kerindidinlọgbon oṣu kanna ni awọn ọmọ ile-iwe Papa ṣe orisirisi ere idaraya ni iranti Alaito.

Balẹ ati awọn ilu na si fi jijẹ ati mimu tẹ awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun, nwọn si jojojo titi di oruganjọ. Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn ogunlọgọ ti nwọn wa si ibi ajọyọ na ni awọn Ọgbẹni J. O. Shoyinka, Adelani Tubosun, Daodu Maiyegun, Olujarẹ Labintan ati awọn enia pataki pataki lati ilu okere wa. Ẹnyin ọmọ Alaito e ku ajoyọ ti baba nyin o. Oluwa yio jẹki a ṣe ọpọlọpọ ajẹyọ o.

## Enia mẹrinla ku ninu ijamba ọkọ oju-omi

LỌKỌJA.

NI aipẹ yi ni awọn ọkọ oju omi meji ṣe ijamba ni Odo-ọya ti o wa lagbegbe Lọkọja, awọn enia ti o si ku sinu ijamba na je mẹrinla. ọmọ ọdun mẹta si wa ninu awọn ti o mu oribọ ninu ijamba na.

Ninu ọkọ akoko ti o ṣeṣe ni ibusọ diẹ si Lọkọja loju omi ni ọkọ elefin U.A.C. kan kolu ọkọ afi opa wa kan ti o nlọ si ilu Baro, enia mẹwa ni o si ku sinu ijamba na, nwọn ko si ri ikọnkọn yọ jade 'nu awọn ti o nwa ọkọ na. ọkan ninu awọn ti o mu oribọ ninu ijamba na ti o

Wo oju ewe kẹrindinlogun

## Awujalẹ titun gb'ade



Oloye S. L. Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni oduro ti o nfun Awujalẹ titun ni iwe—aṣẹ yi.

* * *

IJẸBU-DE.

NI irọlẹ ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ keji oṣu yi ni Ọba Alaiyeluwa Sikiru Adetona ti nwọn ṣeṣe fi je Ọba Awujalẹ Ijẹbu-Ode laipẹ yi ṣe Igbade. Awọn enia ti o si pejọ sibẹ ni ọjọ na ti nwọn ri i pe o gba ade loju won to ọkẹ mẹta enia.

Nigbati ọjọ Ipade na ti ku si dẹdẹ ni gbogbo awọn ọmọ Ijẹbu-Ode ti o wa kakiri idalẹ ti bẹrẹ si ṣe ipalẹmọ, ti nwọn nda orisirisi aṣọ ẹgbẹjọda lati fi ṣe ti eye ajoyọ Igbade na. Beni awọn ti o wa ni ilu Ijẹbu-Ode paapa ati agbegbe rẹ ti ṣe imuraslẹ fun ajoyọ Igbade Ọba wọn na.

Nigbati ọjọ na pe gbogbo awọn enia pataki-pataki ti nwọn ti fi iwe pe lati awọn ilu okere kakiri ti bẹrẹsi de lati owurọ ọjọ na. Nigbati yio fi to agogo mẹta ọsan ẹsẹ gbogbo awọn enia ti pe si ojude Gbọngan Apejọ Itoro nitori ni iwaju Gbọngan na ni nwọn ti ṣe atibaba ati pepele ibiti wọn yio ti gbe ade le Ọba na lori si.

Nigbati o to nkan bi agogo marun, Oloye S. L. Akintọla Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun de pẹlu iyawo rẹ; nigbati o ti ku si dẹdẹ ki Oloye Akintọla ati aya rẹ wọ agbo apejọ na ni okiki ti kan yika ibẹ pe Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun de ilu ndun, ti fere ndun pẹlu fere kakaki lorisirisi, 'gbati o si de awọn Ọlọla S. O. Shonibarẹ, Oloye Okunọwọ Olotu Ijẹbu-Ode ati awọn jankan-jankan si pade Alakoso Ijọba na, nwọn si

Wo oju ewe kẹrindinlogun

WO


Irohin Ilẹ Yoruba loju ewe 3

Ewi Akibu Alarape loju ewe 5

Abayọri Idije Orire Iwọ-Orun loju ewe 6

Aworan Igbade Awujalẹ Tiun lo u ewe 13

Alapara Ibadan di ọṣẹ ti mbọ

# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

## Ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ jẹbi ẹjọ idibo adajọ ni ki o san £73:10 fun ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ

IBADAN.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kerindinlogbọn oṣu ti o kọja yi ni Adajọ Kotu Giga Ibadan tu ẹjọ Idibo ti ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ Ọgbẹni S. A. Layọnu ti o kuna ninu Idibo Apapọ Igbimọ Ijọba Naijiria ti nwọn ṣe ni Ede-Ejigbo pe Ọgbẹni D. A. Ogunlẹyẹ ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti o jagun molu ninu Idibo na pe ki Ijọba tu idibọ na ka nitori ko wọle ni ọna ẹtọ.

Adajọ si tun paṣẹ fun Ọgbẹni S. A. Layọnu pe ki o lọ san owo irinṣẹ ponun mẹtaleladorin ati ṣile mẹwa (£73. 10s), fun Ọgbẹni D. A. Ogunlẹyẹ ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) Ede-Ejigbo ti o m'oke ninu Idibọ na ti nwọn jijọ dije fun aye na.

## ADA—ẸMU JA LORI ỌPẸ, OKU

IBADAN.

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọgbọnjọ oṣu ti o kọja yi ni adaẹmu kan Samuel Adedokun ara Ogbomọṣọ, ẹni ọgbọn ọdun, ti igbe Abule Ikire ni mile mẹdọgbọn si Ibadan ja lori ọpẹ ti o gun ni ẹsẹ bata mejila, ni o ba ku. Ẹsẹkẹsẹ ni nwọn ti gbe oku rẹ lọ si lakulaku ile iwosan Adeọyọ fun abẹwo.


# OSTERMILK

njẹki ọmọ - ọwọ

**nitẹlọrun ! lagbara ! lokun ninu !**



Iya ko le fun ọmọ-ọwọ l'onjẹ mọ, ọpẹlọpẹ agbaalẹ wara Ostermilk. Ostermilk, wara ti o dara lonjẹ, o le mu ki ọmọ-ọwọ rẹ lagbara ki o si ni itẹlọrun pẹlu. O ni afikun onjẹ okun-inu pupọ (extra vitamin-extra iron). Mase daamu, Ostermilk ma a tiwa ni akolun pe ju wara lasan lọ—nitori nwọn nde agolo rẹ pa dada. Sa ti fi omi po Ostermilk fun ọmọ-ọwọ mu . . . . Wa a si ri ọmọ na ti yio ma a rẹrin muṣẹ-muṣẹ.

**OSTERMILK**

MADE BY GLAXO LABORATORIES LTD., GREENFORD, ENGLAND


## Ajiadiẹ-pajẹ wẹwọn ọdun meji

WARRI.

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu kẹta ọdun yi ni Adajọ Agba Kotu kekere kan sọ ọdaran "apẹlẹwọn" kan, Edema Moli, ẹni ọdun marundinladọta si ẹwọn ọdun meji; nitoriti o jẹbi ẹjọ ole ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe o lọ ji adiẹ Ezam Obianika ti iye owo adiẹ na jẹ ṣile merinla (14s.)

Awọn ọlọpa sọ fun Adajọ pe ọdaran na fẹran lati ma a lọ ji adiẹ gbe lalaalẹ nigbati o ba ṣe bi agbepo. Nigbati Adajọ si bi i lere pe kini fẹ lati sọ si ọran yi ki o to gba dajọ, ọdaran na si fi esi pe, mo ni itẹlọrun si iya ti nwọn ba fi jẹ mi. Mo nlọ si ọgba-ẹwọn fun isimi ni.

## ỌBA Ijẹbu-Ifẹ w'aja

IJẸBU-ODE.

NI ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi ni Ọba Alaiyeluwa Hasani Mabadeje Olufẹsọgbade Keji, Ajalọrun Ijẹbu Ifẹ wọ aja ni afin rẹ nigbati o di ẹni ọdun mejileladọrin ti o si ṣe aisan fun igba diẹ. Idile Ọba Olufẹsọgbade ni Ọba ana na jẹ, 'nu oṣu keji ọdun 1943 ni nwọn si fi jẹ Ọba.

Ọba na jẹ ọkan ninu awọn ti o wa si ibi aṣeyẹ yiyan Ọba Alaiyeluwa Sikiru Adetọna, Awujalẹ Ijẹbu Ode ninu oṣu kini ọdun yi. Ọmọ meje ati obirin mẹrin ni o si fi saiye lọ.

## Akinshọla ṣe ọjọ-ibi rẹ

ABẸOKUTA.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu keji ọdun yi ni Ọgbẹni Akinshola ṣe ajọdun ọjọ'bi rẹ ni ile rẹ. Ọgbẹni Abatan ni o si ṣe isin. Ẹsẹ awọn ẹnia pataki pataki ni o pe sibẹ, Ọgbẹni Akinshọla si fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣeyẹ ọjọ na lọrun.

Ajẹijamọdun o.



Ẹniti o duro n apa os ninu aworan yi ni MOGOSHU ti o de ade fun Ọba Alaiyeluwa Sikiru Adetọna, Gbelegbuwa Ijẹbu Ode ni ọjọ Ẹti ti iṣẹ ọjọ kẹi oṣu kẹrin ọdun yi.


**Awọn Iṣaka ati Rorẹ fẹrẹ jẹki o padanu ninu Idije Ẹwa rẹ**



1. Mary ni nwọn ni igbẹkẹle si pe yio bori ninu Idije Ẹwa ni ọjọ Satide. Ṣugbọn ni ọjọ Tọsidẹ o ba a lẹru lati ri i pe iṣaka ati rore ti su yọ loju rẹ lojiji.

2. Mary bu s'ẹkun pe, "ko si ireti fun mi mọ." Iya rẹ sọ pe, "Maṣe ṣe iyọnu ọmọ". "Mo mọ oogun ti yio tete le awọn iṣaka ati rore lọ—Mentholatum.



3. Mary fi Mentholatum ti o npa irora ti o si ngmu oju tutu pa oju rẹ . . nigbati yio fi Satide awọn iṣaka ati rore oju rẹ ti lọ. Awọ ara rẹ fa ni mọra ju ti atẹhinwa lọ.

4. "O wa di ojulowo arẹwa ọmọbirin gan an". Mary gbọ ti ọkan ninu awọn onidajọ idije-ẹwa na sọ nigbati nwọn fun un ni ẹbun Ipo Kini pe "Awọ ara ọmọ yi ma a kuku jọlọ pupọ." Mary ronu pe "Ọpẹlọpẹ Mentholatum" ti o ti ṣẹriba fun Onidajọ na.



Werewere ni awọ-ara yio di jijọlọ yio si kunna pada nigbati o ba fi Mentholatum atura, awura, adẹra pa a. O nṣiṣẹ bi idan—o nwo awọn egbo, iṣaka ati rore san werewere, o daju ko si lewu. Ri i daju pe, Men-tho-lay-tum gan an ni o ra ti o wa ninu awọn agolo ati idẹ bi iru iwọnyi. Maṣe ra awọn adamodi.

Awọn ti o nṣe e nikan ni

**MENTHOLATUM CO. LTD**

(Est. 1889), Slough, England

# MENTHOLATUM

IPARA TI O DARA JU

## Waziri Ibrahim bẹ Ile Iwosan wo ni Ibadan



Ọlọla Waziri Ibrahim, Minista Alamojuto eto Ilera Apapọ Ijọba Naijiria ni Iyaafin Baker Alakoso Ile Iwosan ti ki i fi egbogi ṣe iwosan nfi awọn alaisan han ni Ile-iwosan na yi ni Ibadan.

# AWỌN OYINBO "SOUTH AFRICAN" FI IYA JẸ AWỌN ENIA-DUDU



*Aworan oke yi ni ti Lọya G. B. Akinyẹde ọkan ninu awọn ti o ba awọn sọrọ lori iwa aida awọn Oyinbo South Africa*



Eyi ni awọn ọpọ enia ti nwọn to lati Isaiẹgangan ti nwọn si kọ orin ri iwa aidara awọn oyinbo South Africa si ti ara pako, ti nwọn fi lọ han Alakoso Ijọba Apapọ Naijiria lati fi han fun iwa ipakupa ti awọn npa awọn Enia-Dudu ti o wa si abẹ Ijọba nwọn lori ija igboro ti ko nilari

## Adajọ Kotu Ọba Bauchi paṣẹ ki nwọn da iranṣẹ rẹ ti o gba owo eru duro lẹnu ṣẹ

BAUCHI.

[illegible]

## Ọmọ Naijiria kan fi pọnun meje tanran

LONDON.

[illegible]

## CHIKE OBI NINU EWU MỌTO

EKO.

[illegible]



Aworan oke yi ni ti awọn Akẹkọ ọmọ Enia-dudu ni nu oyinbo ti nwọn kọ iwe akọle is ara pako ti nwọn si to lọ si iwaju ile "South African House" lati fi iwa aidara ti awọn enia nwọn ti o njọba le awọn Enia-dudu South Africa lori, bi nwọn ti ṣe npa wọn ni ipakupa ninu ija igboro ti ko nilari.

## £250,000 ni Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun fẹ yọnda fun Edo College

[illegible]

### Ẹgbẹ … Kaduna ngbero … ọmọde

KADUNA.

[illegible]


## Ẹgbẹ Onișowo Shell Naijiria



Lati ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu March 1960 ni Ẹgbẹ Onișowo
SHELL COMPANY OF WEST AFRICA LIMITED
yio ti pa orukọ wọn da si
THE SHELL COMPANY OF NIGERIA LIMITED

Lati igbati Ẹgbẹ Onișowo Epo na ti nyiṣẹ ni ilẹ yi, ni nwọn ti fi iṣẹ mọ ni Naijiria ati Kamerun nikan, ati nisisiyi nwọn koi ti ni aniyan ṣiṣẹ kọja si awọn ilu miran lẹhin eyi.

SHELL

THE SHELL COMPANY OF NIGERIA LIMITED



DA INU RIRUN DURO

[illegible]

'MILK OF MAGNESIA'

PHILLIPS

O DARA FUN GBOGBO EBI

# ỌLỌRUN MA JẸKI ERO IWAJU DI ERO-ẸHIN?

## ( Lati ọwọ Alakiyesi )

INU mi yio dun bi Olotu ba le gba mi laye ọrọ diẹ yi.

Mo ki gbogbo nyin, ẹnyin ọmọ Ipinlẹ Iwọ-Orun ki Ọlọrun jẹki ilẹ wa na ṣe wa ni rere.

Awọn agba wa ni o ma a npa owe kan, nwọn ni "ọbẹ nfọ ile ara rẹ o ni on mba akọ jẹ, Afopina nṣe ara rẹ nika, o ni on nfi oyun ọkọ jona" ki ẹ fori ji mi o.

Ẹnyin enia wa, ẹ ko ma a muragidigidi ki Kiniwun nyin to ṣalaidi akapo ẹkun ati pe ki aja to ṣalaigun Ẹkun nyin l'ẹṣin, nitoripe, apo ti ẹ fi nko ni idubalẹ yi, o daju gbangba pe,, ti ẹ ba naro tan, ọwọ nyin ko ni to o mọ; nitoripe nigbati ọmọ enia fi ipakọ ara rẹ silẹ ti o si nfi ọwọ tẹ tẹnileni.

Ẹ jọwọ a bẹ nyin ẹ maṣe jẹki a fi iwa ope, ẹtanu, arankan, ikorira, ainifẹ ati imọ-ti-ara-ẹni nikan ba orile-ede wa jẹ, ki a ma si ṣe ti toripe a o ku, lọ la odo fi yana, o tọ ki a ranti awọn ọmọ ẹhin, nitoribẹ, ẹ jeki a lọ sun-gun ki a si sunkaka ki a ronu jinlẹ, ki a si lọ fi imọ ṣekan, ki ẹni iwaju wa ma ba a pada di ẹni-ẹhin.

Ṣe olukuluku ni o nri bi ojo ti nro, ati bi agbara rẹ ti nṣan, o to kia kiyesi ibiti agbara nṣan lọ. Oro to npagi nile ti tun npagi loko yi, ẹnikan mbẹ nidi oro ti o nfi oro, o si tunyẹ ki a mọ daju pe, ohun ti o buru ni, atipe adanu nlanla ni pẹlu pe, ọmọ enia dide o si ṣigun, o jagun o si ṣẹgun, o pada bọ tan o tun wa tinọ bọ ilu. Nje, iru awọn enia bẹ ẹ ni o da bi iru awọn ti Bibeli sọrọ wọn pe:—"Ẹnikẹni ti o bi ninu ọla, ti ko mọle, dabi ẹranko ti o ṣegbe, tabi ere wo ni o wa nibi pe, asa gbogba ipa wa, a nawo, a si nara lati wa ominira, Ọlọrun si ni ki ominira na to wa lọwọ, ṣugbọn a wa a kuna si ibi a ti lo ominira wa na pẹlu alafia ati anfani ara wa: dipo bẹ ẹ nṣe ni a tun bẹrẹsi di ara wa ni igbekun ti o ju igbekun lo, gbogbo wa si gbagbe gbogbo iaalaa wa atẹhinwa, a si tun gbagbe patapata pe, ẹniti o nfi ọmọ ejo ṣire nfi iku ṣire, eyi mu ki awọn agba wa bẹrẹsi ṣe aṣaro nisisiyi lati ba wa fi oju agba yẹ ọrọ wa na wo. Ọlọrun wa, maṣe jẹki agbe tagba sọnu.

Ẹ jọwọ ẹ gbe Bibeli nyin, ki ẹ ṣi awọn Ọba Kini ori kejila ẹsẹ kẹfa titi de ẹkẹtala, ati ẹsẹ kerindinlogun titi de ọkọkandilogun ki ẹ si ka wọn.

Owe awọn Agba wa kan so bayi pe:—"nwọn sọ fun were Imushin pe: ti o ba di ọla ọlola yi, nwon yio ba a fa irun ori re yi. were na si dahun, o ni ti Olorun ba ie jẹki nwọn ba ori on na nile ni" ki Ọlorun jẹki Imoran rere ba ori gbogbo wa nile o.

Ẹni iwaju ni Ọlọrun ti fi wa ṣe ni Ile Nigeria yi, Ọlọrun na ki O jẹki a pada di ẹni ẹhin.

Lagbara Ọlọrun, ti Olotu ba tun le gba mi laye siwaju si a o ma a fi ibiti a nlọ han ara wa. O digba diẹ na o,

# Ayọrisi idije orire

LATI OJU EWE KEFA

Moses Adult Educ Office Agege; Laiwola Adepoju Ile Ojomu fort Odefunke Ile Bale Moro via Ile-Ife; Dominic Agubosin B.O.P. Port Harcourt; Folake Ojutiku 125 Oilsa St Ijebu Ode; Joseph Oladepo care Mr. D. A. Kongi Ogunmola's House Ibadan; Abiodun Aduni 23 Tapa St. Ebute Metta; Patricia James 33 Taiwo St Araromi Apapa.

Oluyemisi Ogunshola Aiyedade L. G. Police Station, Ikire; Yekini Akano, Ile Are Alapaja care Jimo Tulsa Washman Adabo, Iseyin; Tujani Ishola Ile Omomimi, Oke Odo, Iwo; Ejilike Emeuwa Nkwocha Fed. Ministry of Works, Ijora; Wahi-i Awelenje Ojo Giwa Street, Lagos; D. S. Abu care P. U. W. Ewesor 96, Denton Street, Ebute Metta; Anthony L. S. Ubiebi No AY 1 Igbobi Street, Ilesha; Idowu Leo Coastcon Box 13, Nsukka; C. O. Adeyemi ECN Office Oshogbo; S. Aiyelabowo 132 Akano Street, LEDB Shop, Ijemo care Kuroro Box 235; Fatayi Adigun Ile Ali Abawonjo Kudeti; Mallam Ali Dantudu 18, Adamawa Road, Kaduna; Oyebola Gbadebo Apenakufos Compound, Itesi Abeokuta; Mary Olabisi Oke Oja Ile Ife. Augustus Akinlose Akinlaly Customary Court Oshoro Ilutitun; Sherifatu Adeola Owoiya 129 Tokunboh Lagos; Chuku Igwe 8 Agbamu Lane, Warri; D. M. Babayemi care S. O. Ebayemi, Barclays Bank DCO, Apapa; Sakirat Adunni Fahm care S. T. Fahm EDC Office Ilaro; Funlayo Afolarami 70 Oju Olokun Street, Lagos; Comader Oghorada care D. J. Abama L. A. Office, Ughelli.

G. K. Shiwoku 38 Offin Road agos; H. A. Soares Rly Station Lagos; Olagunju Ayorinde 91, Patey Street, Ebute Metta; Badaru Yesufu, B 213 Ajina Street, Offin Shagamu Remo; Omotayo Ogunwo Odosenlu Alaro Postal Agency via Ijebu Ode; F Olawale Apena's Compound Kafanchan; Latifu Bolarinwa Ile Sugilohun Oke Offa Ibadan; C O Gundimibola Clinical Students Hostel UCH Ibadan; Risikatu Apeke SW8/395 Ile Agba Oke Ado Ibadan; J. A. Babatunde Health Office Ibadan; Lasis Adisa Ile Oluwoke Iwo Oke Via Iwo Town; Sikiru Alanda 23 Benin St, Sabongeri Zaria; V. A. Ashake Lajide care A. A. Lajide Magistrate Court Ibadan; George A. Panaki Abisola N6/12 Race Course Rd Sabo Ibadan; Adunle Ajunwon Olomodo S. C. House Tijan; Adekunle Ajunwo Olomodo House care Tijani Aselebe UAC Oyo; Caro N. Alexander 8 Pessu Rd. Warri; Idowu Britto 31 Apapa Road Ebute Metta; Amusa Shittu K. 5 Ogburu St. Ilesha; C. A. Okpetu Taylor Woodrow Bokani Station via Jebba; Taiye Bamgbaiye care I. A. Oyetade Ang. Grammar Sch. Otan Aiyegbaju; Cecilia Bolojoko Dairo care Min of Works and Surveys Ijora, Lagos; Adeniran Adewale, 1, Cole St. Odi Olowo Mushin.

## AKIYESI

Ẹnikẹni ti o ba mọ itan awọn Ọba ilẹ Yoruba, iba ṣe eyiti o ti ku ni tabi eyiti o si wa laaye, ki o kọ o sọwọ, tabi bi nwọn ti ṣe tẹ ilu kọkan do tabi eyikeyi ninu itan iṣẹdalẹ Yoruba. A o si tẹ ẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ ku iṣẹ o.

OLOTU





AMAMA
nfun ni
ni agbara




fi
AMAMA
kun onjẹ
nigba
gbogbo

Manufactured by
Glaxo Laboratories (Nigeria) Ltd.,
Apapa, Lagos.

Trade enquiries: R. E. Harding & Co. Ltd., Lagos, Aba and Kano.
Sub-distributors in Ibadan: Standard City Chemists.

# AWORAN ONITAN



# Awujalę Ijębu-Ode titun Gb'ade



Aworan yi ni ti igbati Oloye T. A. Odutọla Ọgbẹni-Ọja Ijębu-Ode nsin Awujalę Ijębu-Ode lọ lati fi ara han awọn enia rẹ



Aworan yi ni ti igbati Ọba Alaiyeluwa Adetọna, Awujalę Ijębu-Ode jade kuro ni Ipebi lọ gba Ade ni Itoro Ijębu Ode

* * * * * *

Aworan isalę yi ti igbati Oloye Ọbafęmi Awolọwọ, Olori Ęgbę Afęnifęre ati Aṣiwaju Ęgbę Alatako Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria nki Awujalę Ijębu-Ode ku-Ori're lęhin ti o dade tan



## Ęgbę Alakukọ

*(Lati oju we keje)*

Yoruba, nipataki, nilę oṣun, tan Egbę Afęnifęre je ninu ibo gbogbo-gboo ti a di koja yi, bi oba se egbę ti ko fę ire fun ęlomiran ni wọn, o tọ ki nwọn tun bukun owo ori ju bi o ti wa tęlę ri lọ.

Awọn ti nwọn titori owo ori, ti Egbę Afęnifęre ngba, t'o pọju loju wọn, ti nwọn si fi ętan lọ dibo na fun Egbę Alakuko, nwọn wa ri i gbangba nisisiyi wipe, "Ewuro Egbę Afęnifęre, ko fi t'ojo koro", sugbọn, iru awọn ęni bę e ti gbagbe orisirisi anfani ti Egbę Afęnifęre, ti se sinu ilu wọn t'o yato siti ilu miran.

Bi ęnyin onkawe mi ba ranti, ę o ri wipe, Egbę Afęnifęre ti se ileri edinwo owo ori yi kun ileri ti nwọn ti se fun wa, ki a to bere ibo didi, eyiti nwọn so wipe, bi a ba le dibo na fun awọn wọle, ninu ibo gbogbo-gboo ti a di koju, awọn yio se eto owo-ori ti ko ni fi ni enikeni lara, sugbọn gbogbo ileri ti Egbę Afęnifęre nse nigbana ęhin eti awọn Agbokun-sę-ijamba lo mbọ si, sugbọn, loni nkọ, nwọn mu ileri owo ori na sę tabi nwọn ko mu sę? Iti nwọn ti mu ileri wọn na se tọ, nwọn tun se alekun re nipa owo-ori obirin ti nwọn parę patapata, diẹ ni eyi je ninu ileri ti nwọn ti se, ti nwọn nfę mu sę. Ki Oluwa ko sa da ẹmi gbogbo wa si.

Emi Erukobodo ko ni soro pupọ lori aseyori ise Egbę Afęnifęre ju eyi ti mo so yi Ohun ti mo fę ki ęnikookan wa o mo ni wipe:—"Eniti o ba se rere, ni yio gbęsan rere.

# IROHIN LATI OKE-OKUN ATI OKE-ỌYA

## Adajọ sọ ẹniti o lu abilekọ kan sẹwọn oṣu meji

ONITSHA.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi ni Adajọ Kotu Kekere Onitsha ni ki ọdaran kan ,Ndubuilo Okoye lọ fi ogun pọnun (£20) tanran tabi ki o lọ sẹwọn oṣu meji: nitoriti o jẹbi ẹjọ ti awọn ọlọpa ba a ṣe.

Bi ẹjọ na ti ṣe lọ si ni pe ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi ọdaran na bu Theresa Umezoke ninu ile ọrẹ wọn kan, nigbati ariyanjiyan kan si ṣẹlẹ larin Theresa ati ọdaran na ni ọdaran na ba lu u.

## Adajọ ni ki ẹniti o ji tumati lọ sẹwọn oṣu meta

KANO.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kokanlelogun oṣu yi ni Adajọ Kotu kekere sọ ọdaran kan, Haruna Potiskum, ẹni ọdun mẹrinlelogbon ti ko ni ibugbe kan sẹwọn oṣu mẹta oniṣẹ aṣekara nitori pe o jẹbi ẹjọ ole ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe o lọ ji wọn ni igba tumati kan.

# IKIRUN ỌDUN AAWẸ NI ZARIA



*Aworan yı n tı igbatı ogunlọgọ awọn Musulumi nkirun ọdun ipari aawẹ ni Mọṣalaṣi ọdun Zaria ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu ti o kọja yi.*

* * *


# NIGERIAN PORTS AUTHORITY

## PUBLIC NOTICE

NOTICE IS HEREBY GIVEN that the dues and rates payable under the Nigerian Ports Authority (Dues and Rates) Regulations, 1956 (L.N.6 of 1956) as subsequently amended, will be revised on the dates indicated as follows:

DUES ON SHIPS

| | |
|---|---|
| USING A PORT ... | ... 15th April, 1960 |
| SHORE-HANDLING RATES ON IMPORTS AND EXPORTS ... | —do— |
| WHARFAGE RATES ... ... | —do— |
| CRANE RATES ... ... | —do— |
| TOWAGE RATES ... ... | —do— |
| CERTAIN UNPUBLISHED CHARGES (INCLUDING OVERTIME) ... | —do— |
| HARBOUR DUES ... ... | 1st May, 1960 |

2. The revised rates will be published in the Federal Government Gazette as soon as possible and notice of such publication will be given by the Authority in the press.

3. Meanwhile, copies of the proposed revised dues and rates can be inspected (but not to be taken away) at any of the following offices of the Authority:—

| | |
|---|---|
| Lagos | — Secretary's Office, 216, Broad St., Lagos. Chief Traffic & Commercial Manager's Office, Apapa Quay. Dock Superintendent's Office Apapa Quay. Dock Superintendent's Office, Customs Quay. Harbour Master's Office, Old Marine Headquarters, Lagos. Accounts Office, Apapa (adjacent to entrance to Apapa Quay). |
| Port Harcourt | — Port Manager's Office, Customs Road, Port Harcourt. Accounts Office, Port Harcourt. Dockyard Managers's Office Port Harcourt |
| Calabar | — Harbour Master's Office, Calabar. |
| Warri | — Harbour Master's Office, Warri. |
| Victoria | — Harbour Master's Office, Victoria. |

A. R. CORDON
Secretary to the Authority.

26/3/56
N.P.A. Notice N.415.


# Akinyẹlẹ Ọrun're

ACCRA, GHANA.

AGBO sọ'gba nu ni irohin iku Ọgbẹni Kelani Akinyele, ẹniti adape oruko rẹ njẹ "Baba Oniwe" jẹ fun fun t'ọmọde-t'agba ọmọ Yoruba ati Fanti ti mbẹ ni igboro ilu Accra, ni ọjọ kẹrindinlogun oṣu kẹta ọdun yi.

Kilẹ ọjọ keji o to mọ ni ẹsẹ gbogbo ọmọ Yoruba ti mbẹ nigboro Accra ati agbegbe rẹ ti pe ṣọṣọ sinu ile rẹ ni adugbo Saraha, nwọn si sin oku rẹ larin ẹbi ati larin aimoye ojulumọ ni irọlẹ ọjọ keji.

Ọgbẹni Akinyele, jẹ oniṣowo pataki ninu ọmọ Yoruba (Abẹokuta) ti mbẹ ni igboro Accra, Alawada enia ni ologbe Akinyẹle jẹ si t'ọmọde ta'gba, olufokansin enia ni iṣe nigba aiye rẹ pẹlu.

Bi ologbe Akinyẹle ti ni ifẹ si idagba s'oke ilẹ ibi rẹ to, o jẹ ọkan ninu ọmọ Yoruba to' da ẹka Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group), silẹ nigboro Accra. Nipa aajo ati ọyaya rẹ l'ori ọmọ Yoruba t'o ba wọlu na, ni on pẹlu ọmọ-Ọba Adeniran Adefarakan, (Ẹrukobodo ṣe di ọrẹ, ti ọrẹ wọn na si pada di t'ẹgbọn ta'buro titi o fi di ẹni ọrun alakeji a re mabọ.

Ọpọlọpọ awọn enia pataki pataki ni o si tọwọ lọ ki awọn ọmọ ati iyawo t'o fi silẹ, nwọn si tun nki awọn ọrẹ rẹ bi Alhaji Danmegoro, Alagba Rasaki Pedro, Durijaiye Thompson, Raji Onilu Faaji ati gbogbo ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre Oke-Okun. E ku aṣẹhinde eni're.

Ki Oluwa kọ f'orijin in, ki Oluwa o da awọn ọmọ t'o fi silẹ si, ki Oluwa k'o jẹki iru eyi o jinna si ara wọn. Ẹrukobodo, ẹ ku aṣẹhinde ọmọ Liṣabi, ọrun rere.

## Awọn Obirin fẹ fi £7,000 kọ Ile Iwosan kekere kan

AUCHI.

LAIPẸ yi ni awọn Ẹgbẹ 'birin kan, "The Wepa-Wawo Women's Union" ti gbogbo wọn jẹ kiki gbajumọ abileko obirin, ṣe ipinnu ibi ipade kan ti nwọn ṣe laipẹ yi pe, awọn fẹ fi owo ti o to nkan bi ẹdẹgbaarin ponun (£7,000) kọ ile-iwosan kekere kan si ilu Agenebo, ni etido Odo-Ọya (River Niger) f'anfani lilo awọn enia ilu Wepa-Wawo, ni agbegbe Etsako.

## Ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣẹgun Idibo Kalabari

PỌTAKỌTU.

EGBẸ Afẹnifẹre ti tun nlọ siwaju ninu iṣẹgun idibo wọ Igbimọ Ẹkun Ilu Kalabari. Irohin ti o jade lati inu ile-iṣẹ akọwe Ẹgbẹ Afẹnifẹre sọ ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu ti o kọja yi pe Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ko ijoko mẹrilelogun, ti Ẹgbẹ Alakukọ si jẹ mẹwa.

Awọn ijoko Igbimọ mẹfa n'o tun ku ti nwọn nilati tun dije fun ni Kula ati Odua jẹ mẹfa. Agbegbe mẹrin ti o ku ni mile meji Diobu lati fi na Ẹkun Ilu Pọtakọtu siwaju ti nwọn pe nwọn yio ṣe idibo fun ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu ti o kọja yi ni nwọn tun sun ọjọ idibo na si ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu ti o kọja yi.

Ẹniti o ṣe ikede ni Ogbẹni C. Ugwu alaṣẹ etọ idibo ibẹ. Ninu adugbo mejidinlogun titun ti nwọn ṣẹṣẹ da silẹ lati dibo nibẹ mẹrinla ni adugbo ti awọn ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ ti wọle nibẹ lai si ẹniti o ba wọn dijẹ fun un.


*Ẹ ma a ka Iwe*
**IROHIN YORUBA**
*nigbagbogbo fun irohin aladun*

